# NJẸ A TI TUN Ọ BI?

Gbogbo enia ti o ba fẹ lọ si ọrun rere ni "O nilati di atunbi." Notoriti Oluwa Jesu Kristi wipe: "Lootọ, Lootọ ni Mo wi fun ọ, Bikosepe a tun enia bi on ko le ri ijọba Ọlọrun" (Johannu 3:3).

Nigbati a bi ọ si inu aiye, o gba ẹmi iwa-laaye lati ọdọ awọn obi rẹ bakanna ni a tun se nilati tun ọ bi, ki iwọ ki o ba lee gba Ẹmi isọnidi aaye ti Ẹmi Ọlọrun ki iwọ baa le gbadun awọn ohun ti nse ti Ọlọrun ati ti Ọrun.

F'etisilẹ si awọn ọrọ Jesu Kristi wọnyi: "Lootọ, Lootọ ni Mo wi fun ọ, Bikosepe a fi Omi ati Ẹmi bi enia, on ko le wọ ijọba Ọlọrun. Eyiti a bi nipa ti ara, ara ni, eyiti a sibi nipa ti Ẹmi, ẹmi ni. Ki ẹnu ki o mase ya o, nitori Mo wi fun ọ pe, A ko le se alaitun nyin bi" (Johannu 3:5-7).

Atunbi jẹ ibi ti Ẹmi. Nigbati a bi wa si inu aiye yi, a jogun ara ẹsẹ lati ọdọ awọn obi wa, Bibeli si sọ fun wa gbangba wipe a "ti ku nitori irekọja ati ẹsẹ wa" (Efesu 2:1). Ninu

iru ipo bayi, a ko le wọ inu ijọba Ọlọrun rara. Iyipada ni lati wa. Ohun ti Ọmọ Ọlọrun sọ ni pato ti O si fi idi rẹ mulẹ ni wipe: "A nilati tun nyin bi" Atunbi nipa Ẹmi Ọlọrun se pataki, ki a to le ni Ẹmi ti Ọlọrun, ki a si se wa ni yiyẹ fun iwaju Ọlọrun.

Enia ko le funrarẹ ni atunbi. Bakannaa ni ko seese fun u lati ni atunbi yi nipa sise isẹ ẹsin kan tabi omiran, olori ẹsin kankan ko si le fun ni.

Nikodemu, ẹniti Jesu sọ fun wipe: "A nilati tun nyin bi" jẹ ẹlẹsin Farisi, ijoye kan ninu awọn ju ati olukọni ni Israeli, sibẹ o nilo ki a tun bi. Ko yẹ fun ijọba Ọlọrun. Pẹlu iyalẹnu o bere lọwọ Oluwa, "Nkan wọnyi yi o ti se le ri bẹẹ?" Ọrọ kanna ti Jesu Oluwa tẹnumọ muu wa si ipo irẹlẹ lati ipo ẹlẹsin ti o wa tẹlẹ, Nikodemu si ri ara rẹ ni ẹlẹsẹ patapata ti ko yẹ fun ijọba Ọlọrun.

Nigbayi ni o sẹsẹ setan lati gbọ nipa isẹ aigbọdọmase ti ẹlomiran nilati se fun u; "Bi Mose si ti gbe ejo soke li aginju, gẹgẹ bẹẹ li a ko le se alaigbe Ọmọ-enia soke pẹlu; ki ẹnikẹni ti o ba gba A gbọ ki o ma ba segbe, sugbọn ki o le ni iye ainipẹkun" (Johannu 3: 14, 15). A nilati kan Jesu mọ agbelebu nitori ẹsẹ awọn ẹlẹsẹ ki gbogbo ẹnikẹni ti yio ba gbagbọ ninu Rẹ gẹgẹ bi Olugbala, ba le gba iye ainipẹkun.

Ẹmi Ọlọrun ni O nse isẹ atunbi yi ninu ọkan gbogbo awọn ti o ba gba a gbọ. A kan Jesu mọ igi ki awọn ti o gbagbọ le ni iye ninu Ọlọrun. Itumọ ki a fi omi ati ẹmi bi enia niyi: — Nigbati Ọrọ Ọlọrun ba mu ki o ye enia yekeyeke nipa ipo ẹsẹ ati ainireti ti o wa, ati iwẹnumọ ti o le ri gba fun ẹsẹ rẹ ninu agbelebu Jesu Kristi nipa agbara Ẹmi Mimọ, ti enia si gba gbọ, ti o gba Jesu sinu ọkan rẹ, a tun oluwarẹ bi pẹlu Ẹmi Ọlọrun, a si gba a la. On yio gba Ẹmi titun a si sọọ di "alabapin ninu iwa Ọlọrun" (2 Peteru 1:4), O si di ẹda titun ninu Kristi. "Awọn ohun atijọ ti kọja lọ . . . ohun gbogbo si di titun" (2 Korinti 5:17). Iriri ti gbogbo awọn ti a bi nipa ti Ọlọrun nri niyi.

Ọpọlọpọ ni o lero wipe itumọ ki a bi enia "nipa omi ati Ẹmi" ni wipe ki enia ki o se itẹbọmi, sugbọn iwe Mimọ mu ki o daniloju saka wipe Ọrọ Ọlọrun nipasẹ agbara Ẹmi Mimọ ni o nsọni di atunbi. Efesu 5:26 sọ fun wa pato ohun ti omi duro fun: "fi ọrọ wẹẹ mọ ninu omi." "Ki a tun nyin bi, ki ise lati inu iru ti idibajẹ wa, bikose eyiti ki idibajẹ, nipa ọrọ Ọlọrun ti mbẹ laaye ti o si duro." Johannu 1:12-13 sọ wipe iye awọn ti o ti gba Jesu, ti nwọn si ti gba orukọ Rẹ gbọ, ti di Ọmọ Ọlọrun, ẹniti a si ti bi nipa ti Ọlọrun. Ko si ibikankan ti a ti sọ wipe a le tun enia bi nipa itẹbọmi, sugbọn a se pari nipa Ọrọ Ọlọrun ti o nsisẹ ninu ọkan wa nipa agbara Ẹmi Mimọ nipa igbagbọ ninu Kristi.

Ibeere ti o se pataki nipe: Njẹ ati tun ọ bi? Njẹ iyipada ti wa ninu igbesiaiye rẹ bi? Njẹ iwọ ti ni iye ninu Kristi tabi iwọ nfi ete

lasan sin I ni? Bi iwọ ba jẹ kiki ẹlẹsin nikan ti iwọ ko iti ni iriri atunbi, iwọ si jẹ oku ninu ẹsẹ rẹ, iwọ ko si ti ni iye Ọlọrun. Ki a maa se isẹ ẹsin lasan ko mu ohun kohun fun wa.

## "BIKOSEPE A TUN ENIA BI ON KO LE RI IJOBA ỌLỌRUN"

Ma se jafara pẹlu ohun ti o se pataki bi eleyi. Bi o ba se wipe lẹẹkan ni a ti bi ọ, iwọ yio ku ni igba meji (wo Ifihan 20:14). Sugbọn bi a ba ti bi ọ ni igba meji, iwọ yio ku lẹẹkansoso (ayafi bi Oluwa ba de ki iku to mu ọ lọ. Wo Ifihan 2:11; 1 Tessalonika 4:17).

Nitori wipe gbogbo awọn ẹniti ko ba ni atunbi, ni iku keji ti ise iyapa aiyeraiye kuro lọdọ Ọlọrun sinu adagun ina titi lailai duro de, sugbọn fun awọn ẹniti a titun bi, iye ainipẹkun, ati aye lati wa titi lai lọdọ Ọlọrun ninu Paradise yio jẹ ti wọn.

Ewo ni iwọ yan nibẹ?

**Word Of Truth**, P.O Box 1126, Kaduna, Nigeria